# JESU FI IWA AIMOORE FARISI KAN HÀN ÁN

**Luku 7:36-50**

**ẸKỌ 43 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Igbagbọ́ rẹ gbà ọ là; mã lọ li alafia" (Luku 7:50).**

### A Pe Jesu si Ibi Ase

Ọkan ninu awọn Farisi pe Jesu lati wá si ile rẹ̀ fun ounjẹ. Lẹyin gbogbo ohun ti a ti kọ́ nipa iwa awọn Farisi, o ya ni lẹnu ohun ti o tun n fẹ lọdọ Oluwa. O ha n wá ọ̀nà lati ri nnkan kan wi si I? O dabi ẹni pe eyi ni nnkan ti awọn Farisi maa n ṣe, bi o tilẹ jẹ pe awọn diẹ wà ti wọn fẹran Jesu ni tootọ ti wọn si n fi otitọ ọkàn beere nipa ẹkọ Rẹ̀. Nikodemu jẹ́ ọ̀kan ninu wọn. O wá sọdọ Jesu, o si n beere bi a ṣe le ri igbala; a si gbagbọ́ pe o jẹ́ oloootọ pẹlu Ọlọrun, nitori o ṣe iranlọwọ ninu isinku Jesu lẹyin ti a kan An mọ́ agbelebu.

### Ifẹ Jesu fun Awọn Ẹlẹṣẹ

Ṣugbọn bi Simoni, Farisi naa, kò tilẹ fi tọkantọkan fẹran Jesu, nigba gbogbo ni Oun (Jesu) maa n fẹ ṣe iranlọwọ fun awọn eniyan ju bi wọn ti le ro lọ; bi O ba si ri anfaani kan lati ran ẹni kan lọwọ, Oun kò ni lọra lati fara da iwa aitọ́ ti ẹnikẹni le hù si I. O lọ ba awọn ẹlẹṣẹ jẹun ki O ba le sọ fun wọn nipa Ijọba Ọlọrun. Awọn Farisi ta kò O nitori eyi, wọn ro pe O sọ ara Rẹ̀ di alaimọ́ nipa biba awọn ti kò pa ofin awọn Ju nipa ounjẹ mọ́. Wọn pe Jesu ni "ọjẹun, ati ọmuti, ọrẹ́ awọn agbowode ati awọn ẹlẹṣẹ." A dupẹ lọpọlọpọ pe Jesu jẹ́ ọrẹ awọn ẹlẹṣẹ, i ba ma jẹ bẹẹ awa kì ba ti ri igbala!

Boya Jesu mọ̀, nigba ti O gbà lati lọ si ibi àsè ti Farisi naa pe E si, pe obinrin ẹlẹṣẹ nì yoo wá. Ibi pupọ ni a ti kà nipa ọpọlọpọ igba ti Jesu maa n didi ṣe awọn nnkan miiran lai kọ wahala ti yoo ko ba A nitori O mọ pe Oun yoo pade ẹni kan ti ebi n pa fun otitọ: gẹgẹ bi obinrin ará Samaria leti kanga, ati ọkunrin ẹlẹmi eṣu nibi iboji; igba kan wà ti a mu Filippi kuro laaarin ipade isọji ni Samaria lati lọ si iju lati pade iwẹfa nì. Nigba gbogbo ni Jesu maa n ri ọkàn ti o n poungbẹ fun otitọ, yoo si ṣe gbogbo eyi ti O le ṣe lati ṣe iranlọwọ fun eniyan lati ri iye ainipẹkun.

Nigba ti obinrin nì de lati ri Jesu, o wá ni ironupiwada. Pẹlu ẹkun ni o wá nitori o kaanu pupọ fun gbogbo ẹ̀ṣẹ ti o ti ṣẹ̀. "Irobinujẹ ati irora aiya, Ọlọrun, on ni iwọ kì yio gàn" (Orin Dafidi 51:17).

Jesu fẹran rẹ̀ gẹgẹ bi Oun ti maa n fẹran olukuluku ẹlẹṣẹ ti o wá iwaju Rẹ̀ pẹlu ironupiwada. Oun kò kọ̀ nigba ti o bẹ̀rẹ̀ si i fi omije rẹ̀ wẹ ẹsẹ̀ Jesu ti o si n fi irun ori rẹ̀ nu un kuro. Awọn Farisi a maa ṣọra ki ẹlẹṣẹ kan ki o má ṣe fi ara kàn wọn, Farisi yii si wi pe bi Jesu ba jẹ eniyan Ọlọrun Oun i ba ti mọ pe ẹlẹṣẹ ni obinrin yii, ki ba si ti jẹ ki o fọwọ kan Oun. Ṣugbọn Jesu ni Oun wá lati pe awọn ẹlẹṣẹ si ironupiwada, ki i ṣe awọn olododo.

### Ororo Ayọ̀

Obinrin naa mu òrùba alabastar òróró ikunra wá lati fi kun ẹsẹ̀ Jesu. Ni fifọ́ ti o fọ́ apoti ikunra yii, o ni lati lo gbogbo ororo ti o wà ninu rẹ̀. O jẹ́ aṣa ni akoko awọn iṣẹlẹ inu Bibeli lati maa fi ororo tabi ororo ikunra kun ori ati ara, paapaa nigba ọdun ati ni akoko àjọyọ̀. Nitori o jẹ àmi ayọ̀ ati inu didun, awọn eniyan ki i si i lo o nigba ibanujẹ, gẹgẹ bi a ti kà ni 2 Samuẹli 14:2. Awọn ororo ikunra wọnyii jẹ ororo olifi eyi ti wọn ti fi òórun didun ati turari kún; eyi ti awọn ọlọrọ si maa n lò, a maa jẹ olowo iyebiye pupọ. Akoko ayọ̀ nla gan an ni eyi fun obinrin yii nitori a ti dari ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ji i.

Nigba ti Farisi nì n kùn si ohun ti obinrin yii n ṣe, Jesu sọ fun un pe ki i ṣe baalé ile rere. O jẹ iwa ọmọluwabi ni ọjọ wọnni lati pese omi ati aṣọ inura silẹ fun awọn alejo lati wẹ ẹsẹ̀ wọn. Salubata ti ko bo ẹsẹ̀ ni wọn maa n wọ̀, ọna si kun fun ekuru, nitori naa wọn a maa ni itura si i nigba ti a wẹ ẹsẹ̀ wọn. Ṣugbọn Farisi yii kò fun Jesu ni omi lati wẹ ẹsẹ̀ Rẹ̀. Bẹẹ ni kò fi ẹnu ko Jesu lẹnu eyi ti i ṣe ọna ti wọn n gbà ki ara wọn. Obinrin yii ṣe eyi, o ti wẹ ẹsẹ̀ Rẹ̀, o ti fi ẹnu ko ẹsẹ̀ Rẹ̀, o si ti fi ororo kun un, nitori kò ka ara rẹ̀ yẹ lati fi ororo kun Un ni ori.

### Maa Lọ ni Alaafia

Jesu ri ironupiwada ninu ọkàn obinrin naa, O si fun un ni ohun ti o pọ̀ ju ohunkohun ti o le ri ninu ayé lọ: O dari ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ji i. Bawo ni ayọ rẹ ti pọ to nigba ti gbogbo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ lọ, ti o si di alaileeri ati ẹni mimọ́ lẹẹkan si i! Jesu wi fun un pe ki o maa lọ ni alaafia. Gbogbo rukerudo ati aisinmi ti o wà ninu ọkàn rẹ̀ ni o lọ nigba ti Jesu paṣẹ idariji sinu ọkàn rẹ̀. Wò o bi o ti ri ere nlá nlà gbà nigba ti o tọ Jesu wá ni ironupiwada! Farisi nì kò ri ibukun kankan gbà nipa ṣiṣe bi o ti ṣe si Jesu.

Bi ẹni kan ba beere ibeere kan lọwọ Jesu, ọpọlọpọ igba ni Oun ki i dahun lẹsẹ kan naa ṣugbọn yoo fi ibeere dahun ibeere. Nigba ti Farisi nì n sọ ninu ara rẹ̀ pe Jesu ki i ṣe wolii nitori Oun i ba mọ iru eniyan ti obinrin yii ti o wolẹ lẹsẹ Rẹ̀ i ṣe, Oluwa kò gbeja ara Rẹ̀ ṣugbọn O sọ itan kan ti o fi ainifẹ inu ọkàn Simoni hàn. Simoni ri i pe ẹni ti a ba dari ọpọlọpọ ji ni yoo fẹran ẹni ju lọ, ṣugbọn boya ni ọkunrin yii mu owe yii lo fun ara rẹ̀. Kò tilẹ beere pe ki Jesu dari ẹ̀ṣẹ oun ji oun, boya kò tilẹ gba ara rẹ̀ ni ẹlẹṣẹ.

**A Bu Ọla fun Alaini**

Jesu a maa mọ riri ohunkohun ti a ba ṣe fun Un. Njẹ bi ẹni kan kò ba ni ohun pupọ lati fi fun Un n kọ́? Jesu yoo ha ṣe alai fẹran rẹ to bẹẹ bi? A ka nipa opó nì ti o wá sinu Tẹmpili lati fi ọrẹ rẹ̀ sinu iṣura. Awọn ọlọrọ ti ṣiwaju rẹ̀ wá wọn si ti fi owo pupọ sibẹ, ṣugbọn ko jẹ nnkankan fun wọn nitori wọn ni pupọ ju bẹẹ lọ. Ṣugbọn kiki owo idẹ meji pere ni obinrin opó yii ni, o si fi gbogbo rẹ̀ sibẹ. Oluwa sọ nipa rẹ̀ ninu Iwe Mimọ́ pe oun ni ẹni ti a bukun fun. Jesu ki i beere lọwọ wa ju eyi ti a ni lọwọ lati fi silẹ lọ, ṣugbọn wò o bi Oun ti maa n san èrè pada fun wa to nigba ti a ba fi gbogbo ayé wa fun Un.

**Gbogbo Rẹ̀ fun Jesu**

Ẹmma jẹ́ ọmọ kekere ti a mu jade lati ile-ijo kan wá si ile-ẹ̀kọ́ awọn ajihinrere kan. O ṣe aisan lọpọlọpọ, o si wà leti bebe ikú. Awọn obi rẹ̀ jẹ́ alaini lọpọlọpọ. Nigba ti o ku oun nikan ṣoṣo pẹlu iya rẹ̀ àgba, o ni, “Mama agba, jọ ba mi mu apo ifowo-pamọ mi kekere nì wa.” A si mu apo owo kekere naa wa fun un, o si ka owó idẹ ti o wà ninu rẹ̀, o wi pe, “Mama agba, eyi ni owo ti mo ti fi pamọ fun Jesu, lati fun ile-ẹ̀kọ́ ajihinrere. Mama jọwọ ri si i pe gbogbo rẹ̀ jẹ ti Jesu!” Ọmọbinrin kekere yii gba èrè kan naa pẹlu awọn ti o fi gbogbo rẹ̀ fun Jesu nigba ti o rekọja lọ lati wà pẹlu Jesu. O fẹran Rẹ̀ to bẹẹ gẹẹ ti o fẹ ki gbogbo nnkan ti oun ni lati mu silẹ ki o jẹ ti Rẹ̀.

Jesu n fẹ lati ri iru ifẹ bayii ninu ọkàn awọn ọmọ Rẹ̀ ti yoo mu ki wọn fi ọwọ binntin mu ohun ayé yii. Olooto̩ Onigbagbọ a maa to iṣura rẹ jọ si Ọrun, nibi ti wọn kò le rekọja. “Awọn enia si yọ̀, nitori wọn fi tinutinu ṣe iranlọwọ, nitori pẹlu ọkàn pipe ni nwọn fi tinutinu ṣe iranlọwọ fun OLUWA” (1 Kronika 29:9).

**AWỌN IBEERE**

1 Njẹ awọn Farisi fẹran Jesu? Bawo ni wọn ṣe maa n huwa si I?

2 Njẹ Jesu fẹran obinrin ẹlẹṣẹ nì? Oun ha fẹran gbogbo ẹlẹṣẹ?

3 Owe wo ni Jesu pa fun Simoni?

4 Bawo ni Jesu ti fẹ ki a fi fun Oun to?